Chief Secretary to the Govt


# EKO AKETE.

"EMI YIO FI OHUN TI O NDUN MAKUNNU HAN AWON ALAGBARA, NGO SI JE ALAGBAWI AWON ODI."—W. T. STEAD

VOL. VI. No. 2:5 SATURDAY, OCTOBER 6, 1928 4d

The Leading Weekly Vernacular Newspaper in Nigeria.



## White's Radical Gonkiller.

———— :o: ————

(NATIVE.)

[ *A complete cure for old and fresh Gonorrhoea.* ]

When Gonorrhea is not properly cured, it gives rise to other troubles and diseases such as Barreness, Piles, Kidney Diseases, Stricture, Rupture, Rheumatism, Sore-eyes, etc.

N.B.—This Medicine cures Gonorrhea completely in either man or woman, so that no secondary diseases can follow.

Made from pure **Native Herbs,** and sold only by

VICTOR WHITE, ESQ., *Chemist.*

41, Offin Road, Lagos.

PRICE: **Ten Shillings (10/-)** per bottle.

*Packing and Postage 2/6d. extra, to all parts of Nigeria.*

---

EGBOGI ALAWOTAN ATỌSI.

———— :o: ————

[ *Fun Atọsi lailai ati titun.* ]

Ti a ko ba tete wo Atọsi san daradara, o ma ndi enia lọwo lati ṣe abiamọ, o si ma nfa oriṣi arun mi wa, bi:—Jẹdi-jẹdi, Aran, Iju, Ẹda, Ipake, Ase, Lakuregbe, Arun Oju, ati arun mi.

*N.B.*—Egbogi yi nwo Atọsi san lawotan patapata, l o si i jẹ ki o ri aye wu arun mi silẹ.



SECRETARY'S OFFICE 19 OCT. 1928 LAGOS


LOOK FOR
THE PORTRAIT
OF
DrEarlSSloan
SLOAN'S
N & B
FAMILY
LINIMENT
Trade Mark Registered
KILLS PAIN
RELIEVES
Rheumatism
Neuralgia
Sciatica
Sore Gums
Sore Muscles
Sprains
Strains
Swelling
Tender Feet
Toothache
Ulcerated Teeth
Stiffness and
Soreness after
Severe Exertion
General Directions
for External Use
Apply Sloan's Liniment freely, rub very lightly
Keep away from
Fire or Flame
mists and Patent Medicine Dealers
Carton adopted 1916.
s for Great Britain
FASSETT & JOHNSON,
Road, London. E.C.
RED ONLY BY
CORPORATED)
ST. LOUIS. TORONTO. CAN.
ome Office. BOSTON
in United States of America
TO
STOP YOUR
ACHES & PAINS
SIMPLY USE
SLOAN'S LINIMENT
Sold by all Dealers.
Wholesale Fassett & Johnson L[TD]
Clerkenwell R[D] London.
England

*Editor & Proprietor:*—
ADEOYE DENIGA,
*Office* 24, Williams Street,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| Eko. | | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

### ILE JIJO GB'ODE EYI TI JẸ.

Ina kan ṣẹlẹ ni eti *Victoria Road*, ni dede agogo meji oru Satide o si ṣe jamba pupọ. A gbọpe Gambari kan lo tan ina silẹ ti o si ṣeṣi ran mọ agbada—gięgię rẹ, nibẹ ni akara titu s'epo!

### ỌLỌKỌ YI GBA MI O, ME MỌ 'WẸ.

A gbọ pe orin ẹwọ ti awọn ọmọde nkọ leyi ni gbangba Isalẹganga ni Ile-iwe Imale nigbati omi ya si ilẹ gbẹrẹfu na tobẹ ti o fi le gba ọkọ wete kekere kan lati ma mu sọda.

## DUNIYAN—LABARI.

[ LATI ỌWỌ KEKERE-AWO. ]

### DẸMỌ FI GBỌRỌ J' ẸKA, O PE GEDE!!

Ko si botiri ni ayọ ti awọn ẹgbẹ Dẹmọ ti Ebute yọ wa si ile ni ọjọ Jimọ ijẹsan ni ọjọ kejidinlọgbọn oṣu September ti o pari yi, nigbati ibo awọn mẹta (Jones, Moore ati Doherty) ti ẹgbẹ na yan fun Aṣoju ilu ni Igbimọ Aṣofin wọ ile eyiti a ti ri iye ti ibo olukuluku wọn jẹ ka ninu iwe-irohin wa ti Satide to kọja. Boya ẹlomiran ti ko ni iwe "Eko-Akete" ti ọsẹ to kọja le fẹ ni lọsẹ yi nitori na a tun mọnmọ sọ iye ibo wọn lọsẹ yi:—

| | | | |
|---|---|---|---|
| Dokita | C. C. Adenyi-Jones | — — | 888, |
| Lọya | Eric O. Moore | — — | 883, |
| " | T. Adebayọ Doherty | — — | 832. |

A kole sọ bi inu ẹgbẹ yi ti dun to lọ sile, afi ẹniti o ba mbẹ nibẹ lọjọ na, nwọn yangunda lọ si ile Lọya Moore, ile Ọgbẹni Macaulay, ile Lọya Doherty ati ni ile Dokita Jones papa.

Ni gasikiya gbogbo ọmọ-ẹgbẹ yi nwọn duro giri, nwọn ṣe bi ọkunrin nitotọ, nwọn ko fi ẹhin giwa wọn dagun, eyti awọn ẹgbẹ yi tolori-telese wọn ṣe nipa eyi mu ki a fi mọ irufẹ ifẹ pataki ti nwọn ni si Ọgbẹni Macaulay ati si rere ilu yi.

Awa ṣe bi ni eyiti ologbo re ajo boya ile yio di ile ekute, boya awọn ẹgbẹ yio jẹki gbogbo ohun ti ẹgbẹ na ni lati ma ṣe yio rọgbọ, nigasikiya Dẹmọ ti lọ, Ọlọrun fun Ararẹ lo yan. Ọlọrun fi Macaulay ṣe sababi rẹ ni.

Inu wa dun lati ri wipe awọn ẹgbẹ yi fẹrẹ mu ogri si awọn ohun ti ẹgbẹ yi ni ṣe ju igba ti Ọgbẹni Makoli papa mbẹ larin wọn lọ nipa bayi nwọn bu omi pa ina ẹlẹgan nwọn sọ ireti ti awọn ẹlomiran ti wọn le ni si ẹgbẹ na di okibo tabi efifo ọjọkeji ọja—A ki gbogbo ẹgbẹ na patapata nwọn ku ijagunmolu

### LAGOS TOWN COUNCIL.

O dun mọ wa ninu gidigidi lati gburo wipe *Lagos Town Council* ti bi ile-igbẹ *Public Latrine* ti o mbẹ ni Pedro Street tabi Lẹhin-Ọgba wo, ṣugbọn a ko i ti gbọ ibiti nwọn yio paro Ile-igbẹ na si dipo ibiti o ti mbẹ ri na titi di isisiyi.

A ti sọrọ nipasẹ ile-igbẹ na ninu iwe-irohin yi ti ọjọ kẹdọgbọn oṣu August to lọ yi, pe ko yẹ ni ibiti o wa na arara, loju wa, o dabi ẹnipe awọn *Town Council* gba ito ẹnu wa da mi, a si sọ wipe yio dara bi nwọn ba le gbe ile-igbẹ na lo sọ ibomiran ti ko jina tobẹ fun anfani awọn ara adugbo na.

Ẹnikan tiṣẹ wosika nipa ile-igbẹ yi ri ninu iwe yi kanna oluwarẹ njẹ "Ọkanṣoṣo Ajanaku" ninu ọrọ rẹ o ladi bi ile-igbẹ na ko ti ṣe yẹ fun ibẹ arara, o si gba awọn *Town Council* ni amọran ti o niye lori, tani ko mọ irufẹ inira ti orun *smell* igbọnsẹ je lati ma gbọ si imu papa gbogbo igbọnse aiye bi a tilẹ sọ wipe nwọn nbu kanbọliki sinu rẹ lati ma din orun rẹ ku sibẹsibẹ eyi ko di orun igbọnsẹ lọwọ lati gbọ si imu firifiri to bẹ, nitorina a ba ara adugbo na yọ fun orun igbagbogbo ti o ti di baraku fun lati ọjọmọjọ yi wa, eyiti awọn onilu ba wọn ṣe kokari rẹ kuro nisisiyi.

### ATURU TABI CASIKIYA?

A gbọ larin ọsẹ to kọja wipe igi kan tun sọdi ni ọna Yaba, lẹhin ti o jẹ wipe nwọn ti ge igi na lulẹ lati bi ọdun kan, o si ti gbẹ, gbogbo ẹnikẹni ti nlọ la dana, ti o ba jẹ gasikiya, a jẹ wipe igi ọrọ gan ni, irufẹ igi baun ko si yẹ ni itosi ibiti enia gbe wa.

## ỌGBẸNI N. G. J. BALLANTA.

Awọn ẹgbẹ ara Ṣoro ti o bẹ ni ilẹ yi patapata yio ṣe ere aladun kan nipa Ọgbẹni ti a da ruko na ni ọjọ Alaruba ijẹrin ti nṣe ọjọ kẹta oṣu yi ni ile Afari-ogun *Glover Memorial Hall* eyiti nwọn fi Ọlọla Gomina wa Graeme Thomson, G.C.M.G., K.C.B., ṣe Alaga ere na—gẹgẹbi iwe ikede.

## INA GUN ORI ILE F' ẸJU.

Aragbabu ina ni ina ti o ṣẹlẹ ni Victoria Road, ati Seriki Street, ni orn ọjọ Satide ijẹjọ mọju ọjọ *Sunday* ni dede agogo meji; ni eyiti a si sọ wipe ina na njo bayi li a ngbọ igbe awọn ẹniti o damu gbe ẹru wọn le awọn "eranmọlẹru" lọwọ; kisa nla ma ni eyi jẹ loju wa kẹ! ẹnyin ti ẹ nṣe iru iṣẹ buburu bayi, a ni ena kan ajalu o mbẹ ninu idamu bi ohun ini ati ẹmi rẹ yio tiṣe la, awọn janduku ti ko ni anu eṣinṣin kano loju tun nwa igboje tiwọn, ṣugbọn kẹ́ru awọn ẹniti o nṣe iṣẹ eṣu bayi mọ gbangba wipe ọjọ kan ojo o bori ọda—a ki gbogbo awọn ẹniti ajalu ina na kan nwọn ku ewu, ki Oluwa fimọ bẹ o!!

## ASEKO TO!

Oyinbo A. W. S. Rumens ti fi wosika ikede si ode nisisiyi wipe ki awọn ẹniti o nfẹ yan enia si Igbimọ wa tete fi orukọ wọn sl ẹ lati ibẹrẹ oṣu yi titi lọ di ọjọ kẹdogun oṣu yi— afara ni ija ẹkun o!

## AJỌ-IJAGUNMOLU DẸMỌ.

Ipade gbogbo-gbo ti Ijagunmolu Ẹgbẹ Dẹmọ fun ti ibo ti nwọn di ni ijesan ti ibo wọn si mu mbẹ ni ile Afari-ogun *Glover Memorial Hall* ni agogo mẹrin oni ni abẹ alaga Ọlọla Lọya Eric. O. Moore ati awọn Ojoye Onifila-funfuu pẹlu awọn ṣaraki gbogbo ti yio rọgba yi i ka.

Nwọn pe awọn alejo, nwọn si fẹ ki awọn ọmọ ẹgbẹ fi aye silẹ fun awọn Janma ti yio wa fi onjẹ oju fun oju—ckiki ki pa oṣu o!!

## ẸGBẸ SHAMSU-DEEN.

Awọn ẹgbẹ ti a darukọ wọn si oke yi, yio ṣe Isin-Ikore kan ni Mọṣalaṣi Olokodana ni Ebute Mẹta ni dede agogo mẹrin irọlẹ, ni Satide oni ni abẹ alaga Ọgbẹni Lawani Ọlaogun ati awọn iṣangbe rẹ—Ni ọjọ keji tal i ọjọ ọsẹ ọla ni nwọn yio ta ọja ikore wọn, bi a ko ba ri dasi.

---

## IROHIN ỌLỌLA AKARIGBO ATI ỌLỌLA NLA ỌBA ALAPẸRU ỌWỌ KOKALADE IKANṢOṢO AKABA NLA.

Inu wa dun nipa imọran tabi ilanọ tabi iṣẹ rere ti a gbọ lati ọdọ Akarigbo ọlọla nla wa lati ṣe iṣẹ ọna ni ati Ishagamu titi wa de Iju nibiti Afami tabi Iṣẹri Ogun ti Eko. Inu wa tun dun ... Ọba Alapẹru pe o gba ati ṣe iṣẹ rere ... mu ohun anfani wa si ilẹ Rẹmọ o jẹ ... wa. Ina ti o ntan ni ile Eko yio ma ... Shagamu ẹka rẹ yio ma tan de Ipẹru ... Imiran ni ọmọ Shagamu o le lọ sun ... gamu nigbati Ọba wọn ba ṣiwọ agogo mẹjọ ... yio si tun ba wọn bẹrẹ iṣẹ agogo mẹjọ ... keji bakanna. Ẹ o wa ri iṣẹ rere ti Ọba Akarigbo nṣe nisisiyi.

Ira iṣẹ ti Awujalẹ Ọba wa agba patapata ... Ijẹbu Ode eyini ni iṣẹ ọna lati ilu Ijẹbu Ode wa de Ipẹru.

Afi itẹriba bẹ ọlọla nla Awujalẹ kio jọwọ ... dupẹ ni ọwọ ọlọla Akarigbo nipa ọna Mọto ... nfẹ ṣe wa de Iju afami ti Eko tabi Iṣẹri Ogun ... Lagos, ti o dabi ẹnipe mo gbọ wipe wọn ti ... Iṣẹ ọna na nisisiyi. Afi itẹriba bẹ Rev. ... ninu ọla rẹ, ki o jowọ ba wa tọro Adura fun ... nla Akarigbo Ọba wa Agba larin gbogbo Ijọ ... Afi itẹriba bẹ Rev. J. Adewakun ki o jowọ ba ... gba Adura fun Ọlọla Akarigbo ati fun Ọba ... Alapẹru ninu Ijọ C. M. S. Afi itẹriba bẹ ... Kufeji ki o jọwọ ba wa gba Adura fun Ọlọla Akarigbo ati fun Ọlọla nla Ọba Alapẹru nipa ... ọna Eko ti wọn ti ngbiyanju tabi ti wọn ti bẹrẹ ... ṣe nisisiyi gẹgẹ bi ati gbọ ri. Asi ri daju ... wipe ọna na yio ṣe gbogbo wa ni rere ni agbara Ọlọrun. ọna ti a nsọrọ rẹ yi, bi o ba ... iranlọwọ ni o jẹ fun Ijọba Gẹsi ni ọjọ ... Nitorina ki Ọlọrun jọwọ fun wa ni ẹmi gigun ati alafia ara, Amin.

## IROHIN AWỌN ẸGBẸ DẸMỌ, AWỌN ỌLỌLA NLA LAGOS, NIGERIA.

Inu wa dun ọrọ ti Mr. S Akisanya ọmọ Isin Ijẹbu Rẹmọ sọ ni Ipade Ẹgbẹ Dẹmọ ni ọjọ 22/9/28.

Ki ọlọrun jọwọ ba Mr. S Akisanya do uti awọn ọta rẹ. Ki Ọlọrun jọwọ bo aṣiri Mr. S. Akisanya ati ẹmi gigun, Amin.

Kereni Ebute Metta-oti faya o le ni ọsẹ meji nisisiyi. Bi wọn ko ba tuuṣe mo ro pe o le fi ẹmi awọn ọmọde ti o nyi agba wu ewu sinu omi ọsa. Ki Ọlọrun ma jẹki ari; o nfẹ atunṣe ni ati ọwọ Ijọba Gẹsi wa dajudaju gẹgẹ bi emi ti ro.

## IROHIN NI IRANTI IKU BISHOP JOHNSON, ONIWA RERE, ẸNI MIMỌ, ẸNI ỌLỌRUN.

Ni iranti iku Bishop Johnson Ọlọla nla Ijebu Ode.

Bishop Johnson ni alatunṣe Jẹbu Ode nigbati Jẹbu Ode daru nipa oye Ọba Awujalẹ Ademola

Ọlọla nla larin Adekoya Awujalẹ Ọlọla nla julọ. Bishop Johnson ni ẹniti o pe Gomina ninu Ọla rẹ wipe kio wa lọ ba on tun Ilu Jẹbu Ode ṣe iyẹn ni Gomina ṣe mọ pe Ijẹbu Ode daru gẹgẹbi Eko ti daru nisisiyi, ni ati ọwọ Bishop Johnson ni Ọlọla nla Gomina ti lọ fi eto rere si arin Ijẹbu Ode, nitorina abẹ gbogbo ijọ onigbagbọ ati Imale ki wọn jọwọ ba wa gba adura ni iranti Iku Bishop Johnson. Ki Ọlọrun jọwọ ba wa ṣe ona rẹ ni rere, Amin.

Mo yọ pupọ nigbati mo gbọ nipa ti J. K. Coker ọlọla nla nipa eṣu ti o dide si ti Ọlọrun si fun ni Iṣẹgun. eṣu na, nitori ẹru nla ni ọgbẹni J. K. Coker ọlọla nla nru larin Ijọ enia dudu nitorina ki Ọlọrun jọwọ Iṣanu fun Mr. J. K. Coker Ọlọla nla. Ki Ọlọrun jọwọ bawa dupẹ ni owọ Onidajọ Agba ti o ṣe ẹjọ J. K. Coker na, Onidajọ otitọ pataki ni o. Ki Olorun jọwọ wa pẹlu Onidajọ Iẹmi ati ni ara, ati ni gbogbo ọna rẹ, Amin.

Emi ni tiyin nitotọ,

J. A. O. SHOMADE.

---

AWỌN ADUGBO TO DI AMIJẸJẸ.

Abẹ ẹyin (Town Council) ki ẹṣe akiyesi wipe awọn Adugbo wọnyi fẹ titun ṣe.

1. Ibomọ Street.
2. Isalẹagbẹdẹ Street.
3. Pedro Street.
4. Onibudo Street,
5. Idunmagbo Street.

Ati pe kojẹ nkan ti o yẹ arara lati jafara titunṣe wọn nitori o jẹ iṣẹ pataki ninu awọn iṣẹ yin ti ẹni lati ṣe fun alafia (health) awọn enia papa awọn enia to ngbe bẹ.

Ati pẹlupẹlu aisan kan ninu awọn Adugbo na ti ẹyin (Town Council) mọ bi ẹni mọ owo ti ẹ si ye ṣe itọju awọn ọna bẹ ni igba gbogbo. Ati bi irufẹ itọju ti ẹ ṣe fun awọn ọna bẹ ni ọdun diẹ sẹhin.

Ti ẹ fi ọpọlọpọ Idi Panu (Bids Corrugated Sheets) ti o fẹ ma ni iye fi ṣe ọgba yi wọn da, ti ẹyin ni pẹpẹṣẹ ara Ekute ni Aisan Ajakalẹ Arun (Plague) to npa wọn wa, asẹyin wa, asẹyin bọ, Ọgba Panu na ko nise kọ ni Ajakalẹ Arun na tubọ pọ si lasiko na bi; ni oju tiwa (Town Council) ko ti ṣe itọju pataki to yẹ fun awọn Adugbo na to, awa ko wipe ẹyin ko ṣe itọju awọn ọna bẹ, gẹgẹ bi ẹnyin ti tọju enia dudu bi Ile finfin, ati bi irufẹ itọju ti ẹṣe tawi sẹyin.

Ṣugbọn owa yẹ ki Alamodi ma kigbe inu run wun, ki Onişegun fun ni ogun wiwo ara bi?

Awa mọ daju pe lai tun ile awọn Adugbo na ṣe, alafia ko le si ni bẹ, nitorina a bẹ ẹyin Eletu (Town Council) ki ẹ ma jafara lati tun wọn ṣe.

AJUMỌBI.

'IKU ORO RẸ DA, ISA OKU AJINDE RẸ DA'

Anu ṣe wa pupọ lati gbọ iku aya Lọya Hezekiah Onibuwẹ ni South Africa—Obinrin yi jẹ ọmọ Ọgbẹni wa J. B. da Silva ẹniti gbogbo Aguda mọ bi "Juli ti o ta ọti" obinrin yi lo ma nṣi ṣọbu lọkan Ọgbẹni wa Cardoso, Onigbanjo, ni ile ọmọ Ọba Iyagba—ọkọ rẹ yi jẹ aburo Lọya Latunde Johnson ati aburo Mrs. M. B. Vincent—a ba gbogbo awọn ẹbi oloku lọtun losi pin ofo nla yi—Ori ko mọ ibusun bi enia sọ pe South Africa ni Emelia ma lọ sin mi si, a o jiyan ṣugbọn kini gbogbo nkan nlọ ni rere loju Oluwa.

---

Ọgbẹni E. T. Adewọnyin Coker ẹniti o ti wa si Eko lati bi ọsẹ meji ọhun fun amidi rẹ to fẹ pada, o pada lọ si Ile-Ifẹ ni arọ yi pẹlu awọn ẹbi rẹ. Ọkọ a re fo o.—Ba wa ki Baba, Ọni alaiyeluwa fun wa, kabiyesi Ọba.

---

A ba Dokita Adefolu yọ fun bibọ ti o bọ ninu ẹjọ ti nwọn nba ro, o ku ewu, asi ki Lọya Ọlayimika Alakija o ku ohun, a si ki awọn Lọya ẹlẹgbẹrẹ pẹlu wọn ku ṣe—ara Ikija bẹni tirẹ ri, ẹni fi oju di Ọlayimika awo-wo awo!

---

Anu ṣe wa lati ba arakunrin wa Mr. S. A. Kẹkọmi mi ṣe alaro obinrin rẹ ti an pe ni Fatumọ Aduke ẹniti o lọ jẹ ipe Ọlọrun ni 18/9/28 Friday ọsẹ to koja, ki Ọba na fi ẹmi parọ rẹ fun ki irufẹ ba yi ni Ọba jẹ ki o jina si Amin.

---

"A KI KINI IJẸTA."

Mo ki gbogbogbo mo si ki gbogbo ẹnyin Ọmọ-ẹgbẹ ati Igbimọ ẹgbẹ Democratic Party ẹ ku aja bọ ati aja ṣẹgun nipa awọn mẹta ti ẹ yan ti ẹ si dibo fun nipa Igbimọ nla Aṣofin (Legislative Council) awọn ẹni mẹta na ni Jones, Moore ati Doherty. Ọlọrun ko si pẹlu awọn ti ko si ninu ẹgbẹ ṣugbọn ti nwọn si dibo fun ẹgbẹ na. Ọlọrun ko ṣi mu ẹsẹ awọn ẹni mẹta wọn yi duro ti ẹgbẹ giri-giri ti nwọn ba lọ si Igbimọ na, ki a ma ṣẹṣẹ duro wipe wọn nbọ wa jihin fun wa. Ṣugbọn ka mu ni oran ẹdun wipe ki wọn to lọ, ka pepe ka si bere lọwọ wọn wipe ibere wo ni ẹ nmu lọ—bi nwọn ba si de ka bere bakanna wipe esi wo ni wọn fun nyin. Ki wọn si to lọ, eyiti ẹgbẹ ba ri wipe a ṣe ire fun ilu, nwọn le sọ fun wọn wipe ẹ bere nkan bayi bi ẹ ba de ọhun, nitoripe ayan yi ni Ọgbẹni wa Herbert Macauley ma nṣe wipe nkan bayi lo tọ fun ire ilu wa, iyẹn ni kẹ bere, ṣugbọn loni ko si ni arin wa Ọlọrun ko mu bo wa ba wa ni alafia, ṣugbọn kini o, ẹ ṣe iranti yi wipe

ẹgbẹ isalẹ lo nṣe iṣẹ yi fun ( Executive Committee ) nitorina ni mo ṣe ke sode wipe ki gbogbo ẹnyin Igbimọ ati Ọmọ-ẹgbẹ Democratic Party le gbọ, nitori Alagẹmọ ni on bi ọmọ on tan, ai mọ jo di ọwọ rẹ, ẹnyin Agbagba mẹta ti a yan, ẹ ri wahala ẹgbẹ yi, nitori ko si ọmọ ede ninu nyin mọ, ki ori nyin to le wọle, ẹ si ri wipe adura awọn Alufa ati awọn Agbagba ṣẹ le nyin lori, ki wọn to le yan nyin, ko to di pe wọn dibo fun nyin, ẹ o ri ibo nyin bo ti gbe imu le ori ara wọn—Jones 888, Moore 883 Doherty 832, bi ẹ ti duro ti ara nyin yi, bẹ si ni ki ọrọ nyin, ati ibere nyin ko ba ara wọn mu, ki ẹnyin mẹtẹta ki ẹ si ma ṣe aṣaro, ohun ti ẹ nba lọ, bi ẹ ba si de ọhun, ki ẹ duro ti ara nyin giri-giri, bi wọn ba yan meji ninu nyin si Igbimọ to ma nda nkan ro, ki ōhun ẹnyin mejeji si dọgba bakanna, ka ma ri esi ko yi anọ—gẹgẹbi ọrọ Ọgbẹni Akisanya ti sọ fun wa nipa ọrọ Income-Tax.

Awọn ẹni meji ti nwọn da duro fun ara wọn, awọn yẹn ni Ọgbẹni wa J. Bagan Benjamin, C.E. ọkunrin kọkọbọtọ ẹniti abire lọtun losi, ẹniti o ti nṣe ayan pupọ lati igba ti ilu Committee ti wa, ko to di pe a da ẹgbẹ Democratic Party silẹ, ẹniti ibo rẹ jẹ 215 bi o ba jẹ wipe nwọn di ye le ibo ẹnikokan ni, ibo Ọgbẹni yi, iye owo rẹ ju ẹgbẹrun ibo lọ, ṣugbọn a le bere wipe kini ṣe ti Ọgbẹni yi fi da duro fun ara rẹ, tabi kilo ṣe ti o fi kuro ni ẹgbẹ Dẹmọ, "Ṣe bi ko ba ni idi Ewurẹ ki wulẹ de idi opo" ohun to ṣe ti o fi kuro, o sọ ninu iwe rẹ to tẹ jade, chun to ṣe ti ẹgbẹ ko fi yan, ẹ ti gbọ ni Ẹgbẹ Dẹmọ, nitorina nkankan ni inu mi dun si, ohun nipe, lẹhin ti Oyinbo Ọga Agba Munisipa ti sọ awọn ẹni mẹta ti nwọn le tan, awọn ẹgbẹ Dẹmọ tẹ ilu bọ, nwọn si njo ijo ayọ, ṣugbọn wọn ko bu awọn ẹniti wọn ko wọle, eyi yi dara dupọ, o si jẹ ẹkọ rere, nitoripe bi nwọn ba bu wọn yio mu ọpọlọpọ fa sẹhin ni ọjọ miran, nitoripe bi awọn ẹni meji wọnyi, bi wọn ko ba da duro, ko ni si idibo, loju awọn ẹniti ero wọn kuru, wọn a sọ wipe ẹgbẹ-Dẹmọ fi ohun ṣọkan, irẹpọ wọn duro, giri-giri lo jẹki wọn le awọn ẹni ita sa kuro, ṣugbọn loju awọn ẹni ọgbọn ati ero wọn duro lori orukọ ti nwọn npe Dẹmọ ni ita, yio fihan wipe asin nwọn si isi wọn, wipe ki wọn ma lọ yan, ko si ni jẹ ki awa Dẹmọ jigiri si on ti a nṣe.

Ẹni karun ni Lọya Agbebi ti ibo rẹ jẹ 193 bo ba jẹ ẹniti to ri ni lo nhe ẹni, Ajapa ni on ni iba he Oloko, bo ba jẹ wipe nipa mimọ, ẹkọ, iwe to jina haunhaun ni, ẹnyin papa mọ wipe bi orogun iya ẹni ba dara ju iya ẹni lọ a mọ, ṣugbọn kọkọrọ ba ehin aja jẹ nipa ọran ti Lọya Agbebi, ohun nipe ki da si ọrọ ilu, ki ṣe apọn jẹ rẹ lo ma nlọ, aya fi on to ba jẹ mọ Church on ni kan loju wa la mọ wipe o nda si, a ṣẹṣẹ le sọ nipa ti Kotu, iyẹn iṣẹ rẹ—o si ti jẹ Olotu iwe irohin *Law Journal*, ni gbogbo ohun to nmu enia wa nipọ lo ni, Agbebi ko ọkan ninu rẹ, ṣugbọn bo ba jẹ wipe o jẹ ọkan ninu ẹgbẹ Dẹmọ ni, ko si tabi-tabi yio wọle ti ko ni si ikọsẹ nitoripe ẹgbẹ Dẹmọ nikan lo ṣi ẹsẹ mulẹ lode Eko loni, on lo si jẹ Ẹgbẹ ti ilu nfẹ a si ti mọ ti ọla, nipa bẹ bo ba fẹ "Progress" ti ilu yi, ma rope ọdun marun o pẹ titi lọ, "Better late than never" wa mu ṣile meji rẹ wa, ko wọ ẹgbẹ Democratic Party oju rẹ yio to on ti nwọn nṣe nibẹ yala wọn npurọ fun ara wọn ni tabi wọn nsọ otitọ, ati ẹnyin to ku ni ita ẹ ma bọ ẹgbẹ si silẹ fun ẹnikẹni lati wọ, ẹ jọko si ẹnu mimi wipe bi emi wa nibẹ wọn a mu mi dipo Bayọ, koi ti pẹ ju, nitori "Ọna koi ti jin ila koi ti ko" iwọ ma bọ, bi nwọn nṣe otọ nibẹ ni, tabi wọn npurọ, wa le ri daju ṣaka, ọkan rẹ a si balẹ wipe otọ ni wọn nṣe nibẹ.

Lẹkan si mo fẹ gbe ẹnu le ọrọ Ọgbẹni wa J. Bangan Benjamin, C.E. ẹniti o fi ẹgbẹ yi silẹ "Ẹ mọ nlọ, Afe nlọ ẹri ki wọn mai di iho" gbogbo igi ti ko bajẹ arole ile nwọn nyọ wọn sẹhin "Ọrọ mi yi ọlogbọn lo nba wi, nitoripe kini gbogbo awọn tiwọn nlọ wọnyi pataki ni wọn jẹ ninu ẹgbẹ yi, bi otọ ba de ki irọ ko salọ, nigbati Ọgbẹni Benjamin kọ iwe wipe on ko ṣe Sẹkitẹri ẹgbẹ yi mọ, to ba jẹ wipe on ṣe buru ni, tabi o jẹbi ni, Ọgbẹni Herbert Macauley ati sọ wipe ẹniti oni on ko ṣe Sẹkitẹri mọ, ko yẹ ni ọmọ-ẹgbẹ, ẹ ma fi lakaye gbe ọrọ mi, nitoripe awọn omọ-ẹgbẹ miran le ma sọ isọkusọ wipe ẹsẹ lagbaja ko duro, ẹsẹ lakaṣegbe ko duro, gbogbo iwọnyi won ko mu wa ni ẹsun nitoripe ba ni wi, ki ba ni de bẹ, ba ni wi ni awọn onisọkusọ wọnyi, gbogbo wa ni a ma wipe a wa ninu ẹgbẹ Dẹmọ loni, nitotọ gbogbo nyin ni, tani ipo rẹ wa ni ẹlẹgẹ nipa pipe ti ẹgbẹ na npe nigbagbogbo ba ni mọ awọn ọmọran wa mọ, awọn tani wọn nfi ọwọ rẹ wọ pipe ẹgbẹ yi loni, ẹ dani lohun, bi otọ ọrọ ba ki irọ ko gbe ilẹ, loni nibo ni aṣiwaju wa Ọgbẹni Herbert Macauley wa loni yi, bo ti wun ko dẹ to, afi we ile rẹ tabi ko wa ni arin wa, tabi larin awọn ẹbi rẹ, laisi nile rẹ ni ara ẹgbọn rẹ ku ni Olowogbowo, ki Ọlọrun ko gbe si afẹfẹ rere, ki Ọlọrun ko mu Ọgbẹni Herbert Macanlay pada bọ wa ba wa, nipa bẹ ẹnyin "Excutive Committee," ẹnyin oloye, ẹnyin ratibi gbogbo ẹ fi ọran yi si adura ki Ọlọrun ba wa gbe gun, ẹ wo ni akoko ti awọn Shyngle, Moore ati Jones ma lọ si Igbimọ ẹ niran ibura ti Lọya wa igbana ṣe fun wọn pẹlu ẹwu oye rẹ Lọya Mortacute Garney Campbell Thompson ẹniti awọn enia wa npe ni "Ọmọtaku" ẹniti iwe irohin wa npe ni "*our local Lord Birkenhead*" ki lo ti dun to ni ọjọ na, tani ẹgbẹ yi ko wun lati wọ, nitori ori ọmọ lo npe ọmọ wa aiye, loni ibura wo ni a ṣe gẹgẹ bi iwe ofin ẹgbẹ wa ti njẹ awa yan enia gẹgẹ bi ofin ati eto ẹgbẹ, bi a ba fi ofin silẹ ninu ẹgbẹ ofin yẹn lo yẹ ki awa tẹle, a ko ṣo ibura kan fun ẹnikẹni ninu awọn ẹniti ẹgbẹ ngbe sọnu ni wọnyi: Ọgbẹni Adeyẹmọ Alakija Lọya pataki—

Ọgbẹni Osholake Davies ẹniti iwe rẹ ati ẹkọ rẹ ja fanfau ẹniti ẹkọ rẹ nipa ofin ko kẹrẹ, Ọgbẹni Jonathan Collius Zizer, akere koro, ẹniti ki kuro rẹ ṣe oju gbogbo ilu ti ko fara sin, Charles O. Blaize ẹniti akikanju rẹ lati ilu "Committee" wa de ẹgbẹ Dẹmọ ti ko farasin, nipa ọran Ọba wa Eshugbayi Eleko, a ko le sọ inawo rẹ ati ayan rẹ ṣugbọn ka wa sọ wipe Serafu lo jẹ ko kuro, ka ko ila kuro lẹkọ, ẹkọ ki kala—lẹhinna ka wa sọ ti A. Bank Anthony, wahala ati ayan rẹ ninu ẹgbẹ yi ko si ẹniti ko ni alebu tirẹ, ṣugbọn lasiko to wa ninu ẹgbẹ o ko ikoko kan—lẹhin na J. Bagan: Benjamin—nitori na a ko sọ wipe awọn ẹlomiran ko si lẹhin, bi bẹ ni bẹ ri, bi enia fi ọmọ we ọmọ yio lu ọmọ pa, mo fẹ ki awon agbalagba gbe jigi yẹ ọran na wo, ki ẹ wo ibiti o wọ si, ni ipade ti Satide kẹta a ko ri Sẹkitẹri ko wa iyẹn ni, lati wa Ọgbẹni T. H. Jackson ni asiko ti a nwe ewe bi a ti ṣe ma dibo ni a ko ri ko wa, bẹni a ko gbọ wipe o nṣe amudi, irufẹ nkan ba wọnyi, o yẹ ki a ma ṣe akivesi ara nipa rẹ, o tọ ko si ajọ ajọ ko kun ara rẹ lo ntan jẹ, otọ ni yẹn, o wa yẹ wipe bi ede ko yede kan ba de, o ti di yiyọ ni yẹn pataki awọn ẹni ti wa, kini ti awọn ara ita wa yi! Ẹ gba ọrọ mi yẹ wo gidigidi, boya ẹ le ri si ohun ti mo sọ lati-arọ-wa yi—Mo si ki gbogbo ẹgbẹ patapata mo ba wọn yọ mo si yọ fun ara mi pẹlu—Ki Ọlọrun ma jẹ ki ẹgbẹ Dẹmọ yi fọ, ki Oluwa si fi ẹsẹ rẹ mu lẹ ju eyi lọ, amin.

Iwe awọn ẹniti wọn ma fi oruko silẹ ni Munispa fun ẹniti o le yan enia lọ si Igbimọ Aṣofin yi fun ọdun 1929, ati ẹniti wọn le yan o wa nilẹ nisisiyi, ẹ ma jafara a ti lọ fi oruko silẹ, nitori pe ọdọdun ni a ni lati fi orukọ silẹ, nitori gbogbo iyẹn Igbimọ Dẹmọ ẹ san ṣokoto giri a ti lọ gba iwe fun awọn ọmọ Ẹgbẹ ti wọn to lati dibo fun igba miran—A fara ni ija ẹkun, ẹ ma jafara.

Nkan ti mo fẹ fi pari ọrọ yi nipe nkan to ma nfa ẹgbẹ-kẹgbẹ ni ọrọ isokuso ti wọn sọ lẹhin, bi ẹnikẹni ba ṣe nkan ti ko dara ninu ẹgbẹ o yẹ ka fi han awọn agbagba! o ti wun ki ọrọ na jẹ oro ara ẹni to nitori ka ba ara ẹni jẹ lẹhin ko dara to. Oluwa ko ba wa to *gun*.

Emi ni ti nyin nitotọ,
ENIA KO DA BI ALLAH.

---

## ỌRỌ ẸRIN.

Ẹniti a bẹ lori ti nyin'mu, eyiti yio tun ṣe ku! Ki a rin, ki a pọ, yiyẹ ni i yẹni, ṣugbọn bi ti ẹlẹwọn ma kọ ọ!

Ẹniti o goke ki o fa ara rẹ lọwọ, ṣugbọn bi ti ori ọpẹ kọ ṣa!

Ẹniti aba la nbi, ṣugbọn bi ti Ọlọpa kọ, bi ti Akọda kọ, a jẹ pe o ku ohun ti yio tun bi!

"Mo gbọ ti Iyawo, koruna ni ko jẹ ng wa!!"

Ki a maṣe jale, ki a maṣe fẹwọ, bi ki a ri sisi (6d.) loju ọna ki a ma he e ni bi o? Ewọ!!

Bi a nyan Eṣu lodi, o jọun pe ki nwọn fi silẹ kan rubọ sori rẹ ki a mọ ọ loju ni? Agbẹdọ!!

Ke! ki ng ba ọ ke, Adẹtẹ Ẹrunmu, ilu wo ni nwọn ti nyan akara, lai tọwọ bọ epo? (Adẹtẹ fẹ yan akara, elepo, akara ẹri, alakara gbowo tan, Adẹtẹ fẹ tọwọbọ inu awo akara! alakara figbe ta pe, ma tọwọbo o, ma towọbọ o, ni Adẹtẹ dahun pe, ha ha!! tọwọbọpo ni mo fẹ ra kẹ! njẹ ke, ki a jọ ke!!!

OGUNLANA.

---

## INA WỌ'LE OKUNKUN PARADA.



Atupa ti a npe ni "Oṣupa mi" jẹ ojulowo ati pupin atupa hanun ti o si yẹ ilekile, papa ile awọn gbajumọ olowo, a ko le ṣẹṣẹ ma so ti awọn "Dẹngẹ". Agbara rẹ pẹlu agbara atupọ ọdunrun abẹla dede ni, bi ọsan si ni titan rẹ ri ninu ile. Agba ti koi ti lowo gbigba Atupa Ṣango sile ki o ma jafara lati ra atupa meremere yi ti o na electric je

Oriṣi meji lo wa fun tita: ti oni-fadaka ati ti onidẹ

Ẹ lọ yan ti nyin ni Ṣabu Oyinbo KESSLER ni No. 7, Labinjọ Lane

Ẹnyin ara-oke ati ilu miran, ẹ maṣe gbẹhin ki ẹ to ranṣẹ ti nyin, ki ẹ ma ba j'oku ologbo.

---

## Iwe Irawọ 1928 jade,

Ṣile kan abọ ni Office "Eleti-Ọfẹ"

**EKO AKETE**

EKO, SATURDAY, OCTOBER 6, 1928.

## ỌDA OWO, ỌDA OWO.

Dida ti owo da l'Eko lẹnu oṣu melo yi wa tabi lati ibẹrẹ Ọdun yi wa ti jẹ ohun ti a ti nsọ lẹkọkan ninu Iwe-irohin yi; yio san, yio san ni ireti ọgọrọ awọn enia ṣugbọn sibẹsibẹ kaka ki nkan na san tabi ki Owo ati Owo *(trade)* gbera nṣe ni nkan na tubọ nle koko bi oju ẹja si lojojumọ: ti a ba bere ki lo mu ilọsilẹ ohun gbogbo yi wa, ọkan ninu eredi rẹ ko ni ju inu ilu ti ko dun rara lati igbati Ijọba ti mu Eleko lọ kuro ni igboro tabi ãrin wa: ohun miran ti a tun ro pe o mu ọda wa ni ọja Ekurọ ati ti Epo ti ko dabi alara bi ti atijọ mọ: gbogbo awọn ọja bi Ejinrin, Agbadayidi ati awọn igberiko miran ti awọn enia wa ti nsaba lọ ra Ekurọ, Epo, tabi ọja miran wa lati tun wọn ta fun awọn Oyinbo Onişowo l'Eko; ni awọn Oyinbo Onişowo lati ko nibi ti lọ joko ti awọn enia ti nwọn nta awọn ọja wọnyi fun awọn enia dudu ti nlọ ba wọn ṣowo nibẹ lọrun, lọna bayi ọpọlọpọ kọ lo ti "ko'gba sile" ninu awọn Onişowo na wọnyi?

Ohun miran ti o tun mu ailọsiwaju Owo wa ati ọda Owo ni ilu ni iwa "Ohun ti Ẹgbẹ mi ṣe nko ṣai ṣe e" ti o mba pupọ enia ja: ẹ jẹ ki a ṣe apẹrẹ ọrọ ti a nsọ yi: ni iwọn ọdun pupọ sẹhin, o ni iye Şabu ọti *Beer* ti o wa ni ilẹ yi; ṣugbọn loni nkọ, Şabu ọti *Beer* ko le ni ẹgbagbeje bi, bẹ awọn kan ma npowe pe—Owo ki fun Owo lọrun: nilọlọyi, ni ẹnikan sọ ohun ti oju on ri fun wa nipa ti bi Owo ti nfun owo lọrun to, o sọpe *Beer* tita ni pataki iṣẹ on ni adugbo kan nilẹyi o ni, nigbati awọn aladugbo on ri bi on ti nta diẹdiẹ si, o ni afara ko si, o sọpe Şabu *Beer* ti awọn enia wọnyi ti nwọn je aladugbo on nibiti on ntaja yi şi ki oṣu na to pari le ni Şabu mẹdọgbọn! iyoku iregbe, Ọgbẹni yi ni lati ti ilẹkun Şabu rẹ ki o si ba ẹsẹ rẹ sọrọ irufẹ owo miran ti on yio ṣe lati ri onjẹ ojọ—Ẹnyin ẹ tun wo iṣẹ Onigbanjo ti ọgọrọ rọ si nisisiyi melo ni ile ti nwọn leri ta tabi ere ti nwọn rijẹ? Nitotọ: enia le ma ri Iwe "Notice" nwọn lode pe awọn ti gba aṣẹ lati ta ile tabi ilẹ bayi bayi ṣugbọn melo ni ile na ti nwọn le ta nigbẹhingbẹhin nibi pe ki awọn kan tun fi Iwe "Ikilọ" sode pe bi ẹnikẹni ba ra ile tabi ilẹ na oluwarẹ fi owo rẹ gbagi: pupọ ninu awọn enia na ni nwọn nwo ọwọ baba ti nwọn kosi wo ẹsẹ baba: ninu ọgọrọ awọn ti o gba Iwe-aṣẹ lati ma ita gbanjo lọdun tokọja o di melo lo tun le gba Iwe-aṣẹ miran lọdunni? Bi o ti wa ni liki bẹ lo wa ni gbanja: A ha le ṣẹṣẹ ma sọ ti ogidinleje inawo ti o wa fun gbogbo ara ilu fun bukata ojojumọ loju "Orişa bi ifun kosi". Talo le mọ iye awọn ọmọluwabi miran ti nwọn ti wa n'ile lairi iṣẹ ṣe lati ọdun gbọrọ wa

A kesi awọn Aşoju Ilu mẹta ti a ṣẹṣẹ yan ki nwọn maşẹ jẹ ki iṣẹ ti nwọn jẹjẹ pe nwọn yio ṣe fun Ilu mọ ni ori ofin nikan ṣugbọn ki nwọn gba ọrọ ti ọda t'owo ati òwó da lọdunni yẹwo ki nwọn si mura ati ṣe atunṣe ti yio mu irọrun wa fun awọn enia: o si tun yẹ ki awọn enia mẹta wọnyi mã digba rin kakiri awọn ibi ti o "sọnu" ni ilu eyini ni adugbo ti ẹsẹ awọn ẹlomiran ko tẹ ri lati igbati a ti bi silẹ yi tabi lati igbati o ti şigbo wa gbe ilẹ yi, ki nwọn si fi oju arawọn ganni bi ọgọrọ awọn enia miran ti wa ninu inira ati ipati airişẹşẹ to.

A ko le gbe 'nu Ọkọ fa 'kọ.

---

JUST ARRIVED.

**WASU**

ournal of the West African Students' Union of Great Britain.

**1/- per copy.**

Obtainable at the office of:—

**"TIKA-TORE" PRESS,**

**Broad Street, Lagos.**

## ỌRỌ ỌGBẸNI : SAMUEL AKISANYA,
( APA KEJI. )

LATI ỌWỌ KEKERE-AWO.

*(Democratic Party's meeting September 22, 1928.)*

Si Oniwe Irohin *Eko Akete.*

Mo bẹrẹ f'oji,

Ti a ba ri ooun ti ko yẹ, ero wa ni wipe ki a sọ si ode; gẹgẹbi a ti ngbọ nwọn ma npe ede kan wipe ẹnikan ṣoṣo lo da ẹgbẹ yi silẹ ohunkohun ti oluwarẹ ba si sọ, yala o dara fun awọn iyoku tabi ko dara fun wọn, tulasi ti oluwarẹ ni nwọn ma tẹle, mo ro wipe gbogbo ẹnyin ti ẹ mbẹ nihin loni ki yio ṣai gbọ ohun ti mo wi yi, nitoripe oluwarẹ ni ẹgbẹ yi nfẹ ju gẹgẹbi ohun ti nwọn nwi ede eyi le iẹ gasikiya tabi keria ero tiwọn ni iyẹn, nwọn si nro wipe bi oluwarẹ tilẹ papoda ẹgbẹ yi ko ni muro m-.

Ọgbẹni Makọli kosi nihin loni yi, ṣugbọn ẹgbẹ yi si tun pe bakanna ti ko ni iyatọ kan arara, eyi yi le mu ni sọ wipe bi o tilẹ papoda larin wa, bakanna ni ẹgbẹ Dẹmọ yio ma lọ tabi ipapoda Makọli kole di ẹgbẹ yi lọwọ lati jasi ero awọn ẹlomiran.

Ẹ ki yio ṣai ranti ni ọdun karun nigbati a fẹ fi dibo nibi, o mbẹ ninu oyinbo ti o nfẹ ki nwọn dibo fun on lati le lọ si Igbimọ, eyiti awọn enia dudu omiran ko kọ lati dibo fun wọn, nipa ọro ti ngo fẹ gbe ẹnu le yi, awọn ọrẹ mi bi ọgbẹni Eman. Bright le ma jẹri ọrọ mi ati awọn bi ọgbẹni Peter Wright ati awọn ẹlomiran pẹlu; ọgbẹni Bright si da a lohun pe on mbẹ nihin ki o ma sọrọ bọ.

Gẹgẹbi a ti tun pade nihin loni ati gẹgẹbi a ti ndibo nigbati aseko rẹ ba to, a ki iṣe ọbọ tabi omngo fun ibo ti a ndi, nitoripe a jẹ ọdọmọde agbẹdọ ! a mọ ohun ti a nṣe nipa ibo ti a ndi.

Ṣiwaju ki o to dibo fun enia o ni lati ronu ara rẹ jinlẹ daradara, bẹni o si wa fun ẹniti o nfẹ ki awọn enia le dibo fun on lati lọ si Kansulu, o yẹ wipe ki o mura daradara, lati ṣe abojuto ẹru ti ilu yio gbe ka oluwarẹ lori, ki iṣe wipe ki oluwarẹ kuku fẹ gba "Ọlọla" (Honourable) si ori fun lasan.

Ọgbẹni Shyngle da loni, ẹniti a dibo fun ni ọdun karun ti o jẹ Aṣoju ekini fun wa ni Igbimọ, nibo ni ọgbẹni Macaulay gbe wa loni, iru ipo wo ni Dokita Caulcrick tun mbẹ nisisiyi? Gbogbo wọnyi to ohun ti a ni lati mọ si ohun ti tobi.

Anu ṣe mi lati sọ wipe ọgbẹni Shyngle kosi ni aiye mọ lati le da mi lohun awọn ibere ti mba fi si iwaju rẹ, nipa iṣẹ ribiribi rẹ ti o ṣe fun ilu yi ni Igbimọ-Aṣofin, ati pẹlu nipa Dokita Adeniyi-Jones, ẹniti o mbẹ ni ilu Oyinbo nisisiyi, bẹni on papa kole da mi lohun ohun ti mba ma bere lọwọ rẹ nisisiyi.

Oloye Oluwa sọfun wa nihin nigbati o nsọrọ ni ipade ti ẹgbẹ yi ṣe ni Satide keji lọhun, o sọ fun ẹgbẹ yi wipe Dokita Jones gẹgẹbi ko ti si ni ile, ati gẹgẹbi o tiṣe iṣẹ rẹ, ki a dibo fun un.

Ọrọ pataki ni mo fẹ sọ nipasẹ Lọya Moore, ẹniti o jẹ ọkan ninu awọn Aṣoju wa ni Kansulu, o jẹ enia pataki, enia ti o si ni itẹriba lo nṣe, o jẹ ẹniti lakaye rẹ pe daradara ti o si mọ bi a ti nṣe ilu, a tun mu lọtẹ yi lati ṣe Aṣoju wa ni Igbimọ a o si dibo fun un lọjọ Jimọ, ọrọ ti mo nsọ nipa rẹ, mo nsọ gẹgẹbi aṣoju wa nko sọ ni ọrọ afojudi, nitorina ki ẹ jẹki a dibo fun un, nitori o tun fẹ ki a tun ran on lọ ṣe aṣoju wa ni Igbimọ, ibo emi kan ṣoṣo yi, ti nko ba di fun un, o le da duro lati lọ si Igbimọ, ti eyi ba si jẹ ohun ti ko yẹ nyin to, gẹgẹbi mo tiwi nisisiyi nko ladi rẹ han nyin.

*( Koi ti pari. )*

Emi ni ti nyin nitọtọ,
KEKERE-AWO.

---

## *Olusakin's Column.*

CORRECTION.

In the "Eko Akete" of last Saturday, 29th September, 1928, in page 9, under Oluṣakin's Column, £80,000 Fever Victims, *read* 80,000 Fever Victims.

ELECTION RESULTS

Mr. A. W. Rumens, the retiring Officer, *read* Mr. A. W. Rumens the returning Officer.

---

*From the Times Weekly Edition*

AIDE-DE-CAMP TO HIS MAJESTY THE KING.

The King has approved of the appointment of Colonel (temporay Brigadier) H. C. Jackson, C.B., C.M.G., D.S.O., as Aide-de-Camp to the King, in succession to Colonel G. S. G. Crauford, C.B., C.M.G., C.I.E., D.S.O., who has retired.

---

ARCHBISHOP OF YORK.

NOMINATION OF DR. TEMPLE.

The following announcement was issued from 10, Downing-Street last week:—

"The King has been pleased to approve the nomination of the Right Rev. William Temple, D. LITT., D.D., Lord Bishop of Manchester, to the Archbishopric of York when rendered vacant by the translation of the Most Reverend and Right

## ỌRỌ ỌGBẸNI : SAMUEL AKISANYA,
( APA KEJI. )

LATI ỌWỌ KEKERE-AWO.

*(Democratic Party's meeting September 22, 1928.)*

Si Oniwe Irohin *Eko Akete.*

Mo bẹrẹ f'oji,

Ti a ba ri ooun ti ko yẹ, ero wa ni wipe ki a sọ si ode; gẹgẹbi a ti ngbọ nwọn ma npe ede kan wipe ẹnikan ṣoṣo lo da ẹgbẹ yi silẹ ohunkohun ti oluwarẹ ba si sọ, yala o dara fun awọn iyoku tabi ko dara fun wọn, tulasi ti oluwarẹ ni nwọn ma tẹle, mo ro wipe gbogbo ẹnyin ti ẹ mbẹ nihin loni ki yio ṣai gbọ ohun ti mo wi yi, nitoripe oluwarẹ ni ẹgbẹ yi nfẹ ju gẹgẹbi ohun ti nwọn nwi ede eyi le iẹ gasikiya tabi keria ero tiwọn ni iyẹn, nwọn si nro wipe bi oluwarẹ tilẹ papoda ẹgbẹ yi ko ni muro m-.

Ọgbẹni Makọli kosi nihin loni yi, ṣugbọn ẹgbẹ yi si tun pe bakanna ti ko ni iyatọ kan arara, eyi yi le mu ni sọ wipe bi o tilẹ papoda larin wa, bakanna ni ẹgbẹ Dẹmọ yio ma lọ tabi ipapoda Makọli kole di ẹgbẹ yi lọwọ lati jasi ero awọn ẹlomiran.

Ẹ ki yio ṣai ranti ni ọdun karun nigbati a fẹ fi dibo nibi, o mbẹ ninu oyinbo ti o nfẹ ki nwọn dibo fun on lati le lọ si Igbimọ, eyiti awọn enia dudu omiran ko kọ lati dibo fun wọn, nipa ọro ti ngo fẹ gbe ẹnu le yi, awọn ọrẹ mi bi ọgbẹni Eman. Bright le ma jẹri ọrọ mi ati awọn bi ọgbẹni Peter Wright ati awọn ẹlomiran pẹlu; ọgbẹni Bright si da a lohun pe on mbẹ nihin ki o ma sọrọ bọ.

Gẹgẹbi a ti tun pade nihin loni ati gẹgẹbi a ti ndibo nigbati aseko rẹ ba to, a ki iṣe ọbọ tabi omngo fun ibo ti a ndi, nitoripe a jẹ ọdọmọde agbẹdọ ! a mọ ohun ti a nṣe nipa ibo ti a ndi.

Ṣiwaju ki o to dibo fun enia o ni lati ronu ara rẹ jinlẹ daradara, bẹni o si wa fun ẹniti o nfẹ ki awọn enia le dibo fun on lati lọ si Kansulu, o yẹ wipe ki o mura daradara, lati ṣe abojuto ẹru ti ilu yio gbe ka oluwarẹ lori, ki iṣe wipe ki oluwarẹ kuku fẹ gba "Ọlọla" (Honourable) si ori fun lasan.

Ọgbẹni Shyngle da loni, ẹniti a dibo fun ni ọdun karun ti o jẹ Aṣoju ekini fun wa ni Igbimọ, nibo ni ọgbẹni Macaulay gbe wa loni, iru ipo wo ni Dokita Caulcrick tun mbẹ nisisiyi? Gbogbo wọnyi to ohun ti a ni lati mọ si ohun ti tobi.

Anu ṣe mi lati sọ wipe ọgbẹni Shyngle kosi ni aiye mọ lati le da mi lohun awọn ibere ti mba fi si iwaju rẹ, nipa iṣẹ ribiribi rẹ ti o ṣe fun ilu yi ni Igbimọ-Aṣofin, ati pẹlu nipa Dokita Adeniyi-Jones, ẹniti o mbẹ ni ilu Oyinbo nisisiyi, bẹni on papa kole da mi lohun ohun ti mba ma bere lọwọ rẹ nisisiyi.

Oloye Oluwa sọfun wa nihin nigbati o nsọrọ ni ipade ti ẹgbẹ yi ṣe ni Satide keji lọhun, o sọ fun ẹgbẹ yi wipe Dokita Jones gẹgẹbi ko ti si ni ile, ati gẹgẹbi o tiṣe iṣẹ rẹ, ki a dibo fun un.

Ọrọ pataki ni mo fẹ sọ nipasẹ Lọya Moore, ẹniti o jẹ ọkan ninu awọn Aṣoju wa ni Kansulu, o jẹ enia pataki, enia ti o si ni itẹriba lo nṣe, o jẹ ẹniti lakaye rẹ pe daradara ti o si mọ bi a ti nṣe ilu, a tun mu lọtẹ yi lati ṣe Aṣoju wa ni Igbimọ a o si dibo fun un lọjọ Jimọ, ọrọ ti mo nsọ nipa rẹ, mo nsọ gẹgẹbi aṣoju wa nko sọ ni ọrọ afojudi, nitorina ki ẹ jẹki a dibo fun un, nitori o tun fẹ ki a tun ran on lọ ṣe aṣoju wa ni Igbimọ, ibo emi kan ṣoṣo yi, ti nko ba di fun un, o le da duro lati lọ si Igbimọ, ti eyi ba si jẹ ohun ti ko ye nyin to, gẹgẹbi mo tiwi nisisiyi nko ladi rẹ han nyin.

*( Koi ti pari. )*

Emi ni ti nyin nitotọ,
KEKERE-AWO.

---

## *Olusakin's Column.*

### CORRECTION.

In the "Eko Akete" of last Saturday, 29th September, 1928, in page 9, under Oluṣakin's Column, £80,000 Fever Victims, *read* 80,000 Fever Victims.

### ELECTION RESULTS

Mr. A. W. Rumens, the retiring Officer, *read* Mr. A. W. Rumens the returning Officer.

---

### *From the Times Weekly Edition*

### AIDE-DE-CAMP TO HIS MAJESTY THE KING.

The King has approved of the appointment of Colonel (temporay Brigadier) H. C. Jackson, C.B., C.M.G., D.S.O., as Aide-de-Camp to the King, in succession to Colonel G. S. G. Crauford, C.B., C.M.G., C.I.E., D.S.O., who has retired.

---

### ARCHBISHOP OF YORK.

### NOMINATION OF DR. TEMPLE.

The following announcement was issued from 10, Downing-Street last week:—

"The King has been pleased to approve the nomination of the Right Rev. William Temple, D. LITT., D.D., Lord Bishop of Manchester, to the Archbishopric of York when rendered vacant by the translation of the Most Reverend and Right

Honourable Cosmo Gordon Lang, D.D., Lord Archbishop of York, Primate of England and Metropolitan, to the Archbishopric of Cantebury."

NEW BISHOP OF MANCHESTER.

DR. GUY WARMAN.

The following announcement was issued from 10, Downing Street last week:—

"The King has been pleased to approve the appointment of the Right Reverend Frederick Sumpter Guy Warman, D.D., Lord Bishop of Chelmsford, to the Bishopric of Manchester when rendered vacant by the translation of the Right Rev. William Temple, D. LITT, D.D., Lord Bishop of Manchester, to the Archbishopric of York."

---

MR. AMEER ALI, THE GREAT MOSLEM LEADER, AND THE FIRST INDIAN MEMBER OF THE PRIVY COUNCIL.

We regret to announce that Mr. Ameer Ali, the eminent Indian jurist and Moslem thinker and leader, died suddenly at his Sussex House, Pollingfold Manor, Rudgwick, on Friday, at the age of 79.—*The Times Weekly Edition 9/8/28.*

---

LEGISLATIVE COUNCIL OF NIGERIA.

**Table Of Unofficial Members, 1928.**

According to *Nigeria Gazette Extraordinary*, dated 1st October, 1928, the following Gentlemen will represent the Unofficial Members of the Legislative Council of Nigeria:—

NOMINATED MEMBERS.

Sir Kitoyi Ajasa, KT., O.B.E., Lagos, Nigeria; Angus Leicester Butler, Esq., Jos, Nigeria; Chief Isaac Okechuku Mba, Onitsha, Nigeria; Samuel Chukuma, Obianwu, Esq., Onitsha, Nigeria; George Graham Paul, Esq., B.L., Calabar, Nigeria, Samuel Herbert Pearse, Esq., F.R.G.S. Abeokuta, Nigeria; Mark Pepple Jaja, Esq., Opobo, Nigeria, Henry Stewart Feggetter, Esq., Lagos, Nigeria; Lewis Medwin Herapath, Esq., Lagos, Nigeria; Leonard White, Esq., Port Harcourt, Nigeria.

---

ELECTED MEMBERS REPRESENTING THE MUNICIPAL AREA OF LAGOS.

Dr. Curtis Crispin Adeniyi-Jones M.B., B.S., Lagos; Eric Ọlawolu Moore, Esq., B.L., Lagos; Theophilus Adebayo Doherty, Esq., B.L., Lagos.

MEMBER REPRESENTING CALABAR.

Charles Warmer Henshaw Clinton, Esq., B.L., Calabar, Nigeria.

ADMINISTRATIVE CHANGES.

According to a Government Notice in the *Extraordinary Gazette* of the 2nd October, 1928, His Excellency Sir Graeme Thomson, G.C.M.G., K.C.B., being prevented through illness from acting in the duties of his office, the Honourable Sir Frank Baddeley, Kt., C.M.G., B.E., Chief Secretary to the Government has taken the prescribed oaths and assumed the administration of the Colony and Protectorate of Nigeria.

The following acting appointments are [illegible] issued last Tuesday, Mr. H. M-M. Moore, Deputy Chief, to be Chief Secretary to the Government and Mr. K. L. Hall, to be Deputy Chief Secretary to the Government.

OLUṢAKIN.

---

ORI IV.

IṢẸ.

(*Translated from "Character by Dr. Smiles"*)

APA KẸTADILOGUN.

---

Nigbati nwọn wa ri pe Oloye enia ni ni *Duke of Ferrara* wa ran lọ si Rome ati si ilu miran fun iṣẹ pataki. Lẹhin eyi ni nwọn fi jẹ balẹ ilu agbara Oke kan; awọn enia agbegbe ilu yi jẹ jagidi-jagan, oniyọnu enia. Ṣugbọn o se wọn rọ; o si wa ṣe ẹtọ pẹlu wọn, tobẹ ti ilu wa rọ wọku-wọku ti aiya awọn ara ilu si balẹ. Ani awọn onijadi ilu na tilẹ pada wa wari fun. Ni ọjọ kan, ti o bọ si ọwọ awọn enia buruku wọnyi ni agbara ọke, ti nwọn ra mu. Nigbati o darukọ ara rẹ fun wọn lọgan ni ọwọ wọn bọ, nwọn bẹ ki o jẹ ki awọn sin ki nwọn ṣe itọju rẹ de ibikibi ti o nlọ. Bẹna ni, ni awọn ilu miran, Vattel ti o ṣe iwe ti a npe ni *(Rights of Nations)* ṣiṣẹ Aṣoju-Ọba, o si jẹ oniṣẹ ti ko si ekeji rẹ. Rabelais jẹ Oniṣegun *(Physician)* ti o mọ iṣẹ; Schiller jẹ Oniṣegun ti o mọ ilo arun *(Surgeon)*; iṣẹ agbebọn ni *Cervantes, Lope de Vega, Calderon, Camoens, Descartes, Maupertius, La Rochefoucauld, Lacepede* ati *Lamrak*, kọkọ ṣẹ.

Ni ilu ti awa papa, awọn ẹniti o jẹ pe nipa iwe ti nwọn ṣe ni a fi mọ wọn loni, ni iṣẹ wọn lọwọ eyiti nwọn nṣe jẹun. Iṣẹ

agbẹdẹ fadaka ati ti wura ni Lillo ṣe titi ni *Poultry* : nigbati o ba ṣiwọ a ma kọ iwe-ere ninu eyiti a ri awọn eyiti ko ṣe fi ọwọ rọ sẹhin. Aṣọ ni Isaak Wilton nta ni Fleet Street, nigbati o ba ṣiwọ a kunri mọ iwe kika o nkọ opọlọpọ Ọgbọn ti o wa fi kọ Iwe-itan. Ẹṣin ni De Foe ngba ta, lẹhin na o nṣe biriki ati awo ti a fi nbọ ile, o ṣiṣẹ ni ile ọja tita, o ṣe iwe, o si wa ṣiṣẹ ilu.

Samuel Richardson kan akanpọ iṣẹ iwe-ṣiṣe ati ti Owo-ṣiṣe ; lẹhinkule ile ọja tita rẹ ni Salisbury Court, Fleeṣ Street ni o nṣe awọn iwe rẹ, a wa ko wọn wa ta ninu ile ọja rẹ. Bẹna ni William Hubon ko fi iṣẹ iwe tita ati iwe ṣiṣe pọ.

Ninu iwe itan ti ara rẹ ti o ṣe, o sọ pe, enia le gbe adọta ọdun laiye sibẹ ki o ma mọ iwa ara rẹ.

On ko mọ pe on ni Oye awọn nkan atijọ afi nigbati gbogbo enia sọ bẹ, lẹhin igbati nwọn ka iwe ti on ṣe eyiti a npe ni "History of Birmingham," nigbana ni on papa wa to mọ. Bẹna ni Benjamin Franklin jẹ Olokiki lọna ti iṣẹ iwe-titẹ at iwe-tita-onjẹ Oṣewe, elero ati Oṣelu ni.

*Translated by*

ADEYINKA AJAGBE-ỌSA


# NIGERIAN RAILWAY

## *Numerous Improvements*

Commencing MONDAY, 1st OCTOBER, 1928.

Additional and better Trains.

Cheaper Return Fares.

***Easier Regulations Regarding Luggage, Produce, etc.***

Apply to your Local Station Master for Pamphlet.

***Issued Free of Charge.***

Giving Full Particulars of all Trains between

***IDDO and LAFENWA***

New Reduced Fares and Revised Luggage Regulations.

***"Travel by Rail"***

"SAFETY" "SPEED"

"REGULARITY."

## *Use Yaro for your baby!*

All experienced mothers give testimony in praise of "Yaro" as an indispensable 'Preservative' for 'Babies.' Yaro has no equal in suppressing those complaints which make infants feel uneasy, especially during their critical teething period. Trust Yaro for all infants' complaints and use it for your baby. Price per bottle 3/3d & 2/3d.

## *Increased health for 3/- only.*

"Life Tonic Tablet" imparts tone and vigour to the body, renews every atom of the flesh, prevents brain fatigue and brings indescribable comfort to all mental workers. Price 3/- per bottle.

## *A chance for female sufferers.*

Wireless Female Pills, the latest Scientific Discovery, have answered divers cases of functional compl[illegible]ints of disorders peculiar to women. These Pills serve as an effective fertiliser against barreness. Give "Wireless Female Pills" a trial and prove its reliability.

Our Anti-Plague Disinfectant Fluid kills dangerous flies, bugs, cockroaches, etc., etc. 1/- and 1/6d per bottle.

### *Anti-Gon Pills.*

Get rid of veneareal diseases before they get rid of you by using Anti-Gon Pills—a reliable antisceptic against Gonorhea. 3/- per bottle.

WE ALSO STOCK:—

Glaxo (large and small sizes)
Vitafer—Brain Tonic
Walk Easy Anti-Rheumatic Salt 3/6 & 2/-
Pile Pills 1/6
Vibrona Wine 7/6
Lactogen
Kalzana
Effective Pile Remedy 7/6
Back and Kidney Pills 2/-
Zotal 1/6 & 2/6

*Obtainable at:—*

# IYIN OLUWA MEDICINE STORES

*Head Office*:—88, Broad Street, Lagos,
*Branches*:—6, Martins Street,
41, Alli Street, Faji Market,
109, Griffith Street, Ebute Metta.


Disinfectant Soap of Unrivalled Quality
Use Magnet Carbolic Soap in your home—it refreshes the skin and guards against infection. Made in three sizes, and obtainable everywhere.
MAGNET
Carbolic Soap Tablets
MAGNET
SOAP
WEST AFRICAN SOAP COMPANY LIMITED, APAPA.

## White's Golden Male Tonic

DOUBLE STRENGTH).

**Whenver a** woman has not been in the family **way for a** long time, the fault is usually set down **to some** disease or other in her generative organs.

Now while it is true that many women suffer **from** disease, yet many times the fault lies with **the man**, owing to weakness or some other disease **of the** male organs of generation. White's Golden **Male** Tonic (Double-Strength) is calculated to **give** full vigour to the man, and to remove all **diseases** which prevent breeding. Every sensible **man** ought to use two bottles every month, to **cure** or prevent weakness of the generative organs.

Made and sold only by VICTOR WHITE, Esq.,
*The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos.*
*N.B.*—NOT OBTAINABLE ELSEWHERE.
"Shake the Bottle."

### ARẸMỌ FUN ỌKUNRIN.

Nigbati obinrin ko ba tete loyun, a ma nro pe **ara** obinrin na nikan ni arun wa. Ṣugbọn nigba **pupọ** ni o nję pe ara ọkunrin ni arun wa. Egbogi **yi dara** pupọ fun Arę, Ẹda ati gbogbo arun ti ki **ję ki** ọkunrin şe abiamọ.

*N.B.*—O yę ki gbogbo ọkunrin ma lo igo meji-meji loşoşu—Işę ti egbogi na nşe ni ara ko şe royin.

Price TEN SHILLINGS (10s) per bottle.
*Postage 2/6 extra.*

## White's Golden Female Tonic

A splended Remedy for Female diseases such **as**:—Barrenness, Weakness, Painfull and Irregular, Menstruation Leucorrhœa (Whites) Cramps, Ovarian, Neuralgia, Inflammation of the Ovaries. A Tendency to Miscarriage etc, etc.

Made and sold only by VICTOR WHITE Esq.
41, Offin Road, Lagos.
*N.B:—Not obtainable elsewhere.*

### GBOGBONIŞE FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun Aboyun, Iju, Ẹda, **Aran**, Oyun ti o ba fę baję, ati orişirişi arun mi ti **ki** ję ki obinrin bimọ.

PRICE 10/- PER BOTTLE.
**Postage 2/6 extra.**

WHITE'S

## WONDERFUL BRAIN TONIC.

This medicine stimulates and rebuilds the brain in such a way, that the regular user is able to do many times the usual amount of Brainwork that he used to do, before using it. To Brainworkers and those who have examinations to pass, it is a boon.

Made and sold only by SAMUEL VICTOR WHITE, Esq.
41, OFFIN ROAD, LAGOS.

Large size 5/- per bottle. Packing and Postage 2/6 extra.
Small size, 2/6 per bottle. Packing and Postage 1/6 extra.

N.B.—*Scholars should not be without it.*

### EGBOGI IṢỌYE.

Egbogi yi dara pupọ fun awọn ọmọ-ile-iwe awọn ti o nfi iwe şişę ati gbogbo awọn ti o ba ni lati lọ fun idanwo.

*Iba şe ọmọde tabi agbalagba.*

## White's Golden Blood Restorer

*(A Native preparation for Women.)*

This medicine is an excellent remedy or Insufficiency or Loss of the monthly courses, Tumour in the Womb, False Pregnancy, Catarrh of the Womb, Various Runnings or Morbid Discharges from the Womb (especially those that are long-standing).

Sick Headaches, Dizziness, etc., etc.

Made and sold only by

VICTOR WHITE, ESQ, *Chemist,*
The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos

"SHAKE THE BOTTLE".

Price TEN SHILLINGS (10/-) per bottle.

*Packing and Postage 2/6 extra, to any part of Nigeria.*

### EGBOGI ILANA ẸJẸ FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun obinrin ti ko ba ri nkan oşu rę mọ (lalai to aseko), nkan obinrin ti ko ba pọ to. Aşę Ewurę pipọju, Ẹda ti o ba gbo, Ẹyo, Oyun-koyun. Oyun ti ko ba dagba, Oyi, Ẹsanri ni akoko hela, Aran ati Iju.

## HORSFIELD'S

The well known suppliers of all classes of goods under the registered Trade "ZODIAC" Mark.

Call and see our Agent and give your orders to:—

MR. MOSES O. COKER,

Port Novo Market Street, Lagos.

who has samples every mail of all the latest styles of fancy and other goods, including our REGISTERED Palm Tree and Feather Embroideries.

We supply everything.

J. J. HORSFIELD & CO.,
( Manchester ) Limited,
65, George Street,
Manchester.

## GOOD MARKET.

Gonorrhea Specific, Moloke Mone, A. & D. Bula Matadi for health-restoring purposes: these Medicines are on sale at Mr. H. Campos's First Class Shop, 37, Odunlami Street, Lagos. The Specifie acts like Magic : has cured many obstinate cases, and *will cure yours just the same*, if any.

Cheap Goods! Superior Quality!! Quiok Fortune!!!

*Cable Address*:—"WHITE LAGOS".

MR J. T. AKIRẸMI WHITE
P.O. Box 82
20, Balogun & Breadfruit Streets
or
41, Offin Road, Lagos.

## Indents House.

Import of General Lines
Export of Produce Commission Agencies endetaken.

Correspondence invited.

With over 22 years' experience in this line of business.

Mr. White's well-known connexion with reliable Firms in Europe is a matter of common knowledge to his clients.

**A Trial is Solicited.**

When replying advertisers please mention *Eko Akete*

## TO LET.

**One Splendid Pleasure Car**

No. L2754.

***Always at everybody's service at Tinubu Square.***

For Terms, Apply to —

A. B. Williams,
14, Bishop Street, Lagos.

## ILE OWO OYINBO

# JOHN RADCLIFFE

### Ni No. 63, Ehingbeti, Eko.

: o :

Ile-owo ti o wuyi fun ọja meremere bi Ṣẹda, aṣọ Yọmini ati aṣọ ti a fi ẹlẹya Oyinbo gbaleti.

Ẹ wa bẹ orişirişi ọja wa wo ni Ile-owo wa titun to kọju si Ile Niger ni No. 63, Ẹhingbẹti.

Aşọ lorişirişi ni aşetejọ: aṣọ Ṣẹda ati Siliki mbẹ bi aba, awọn wọnyi jẹ eyiti awọn onibara ṣa ti nwọn si ti sami si fun ra wọn. Aṣọ lami-titi ti a npe ni Ṣantọnu nkọlu 'ra wọn.

Agbalẹtu ni gbogbo ọja wa fun didara wọn.

Pọ ọ si ni owo wọn.


PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING PRESS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.